Owe

KITA-KITA OMO TI ARISIKI KI A SISE BI ERU KO DA NKAN

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

Asoje

NIA BI IY KOS TAN JE S'OMO OLOMO LORE

OL. XIII No 703 LAGOS SATURDAY AUGUST 26 - SEPTEMBER 1, 1961. KOBO MEJI (2d)

# OLE JI OWO PELU ESE MOTO, O TI ONISE-ORU MONU MOTO, O SALO.

Awon olopa - inu ti'u Eko ni a gbo wipe, ever ti bere si wa ole ologbon ewe kan ti o lo lu Dokita kan n Jibiti gba ponun mejila pelu irin ese Moto re ati taya kan.

Iwe irohin awon olo a ti o jade nilu Eko e wipe oku rin ti Dokita ko mori, ni o lo ba Dokita ra, l'ona tire ni Surulere, ti o si so fun wipe Ogbeni Haastrup l'o ran on wa gba owo ponun mejila lati fi ra taya Mot .

Dokita na si fun lowo na ati moto re, o fi ( nise oru ti o nsele re le lehin lati ba lo gegebi ko ti mori, sugbon ko pada wa bikose igbati o da moto pada ti o ti Onise-oru (Nightwatchman) mo inu moto ti ni jegun ba f'ese fe, o salo bambam.

## Adajo Pase Ki Iyawo San Ponun Metalelogorin

AGOEKTI -- Ogbeni Olu Adekunle ni o pe Iyafin Remi Oluyode lejo si Kotu ibile wipe ki Kotu ba on gba ponun metalelogorin ati sile meji owo ti on na fun obinrin na labati o se adehun lati fi on gbeyawo pe, ti o si ba adehun na je.

Ogbeni Adekunle ro o p ninu odun 1959, Iyafin Oluyode gba lati fe on lehinti o si ti kowe adehun ti on ti siwaju awon, fun on ni owo ti ar p ghogbo re je ponun metale-logorin ati sile meji (£83: 2/-).

Iyafin Oluyode ro tiru eji tire wipe, ore ni on pelu Ogbeni Adekunle se, atipe owo ti o na fun on je ey.ti o fi ba on d'ore ni asiko ti awon nsore.

Adajo Kotu ibile so wipe o buru pupo ki obinrin lo fe oko miran lehinti o ti gba owo gobgyi lowo okunrin kan ti o ti gbe gbogbo okan re le lori. O si pase ki Iyafin Oluyode lo san ponun metale-logorin ati sile meji na pada fun Ogbeni Olu Adekuule lairin ogbon ojo.

Enyin otiurin ti o ngba lowo Asa ti e tun ngba lowo Awodi, e fi eyi kogbon.

THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933

Paid up Capital £3,160,000

Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE

37, MARINA, LAGOS NIGERIA.

28 Branches Throughout Nigeria Including IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA ILARO, BENIN-CITY, WARRI SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2

Manager : F. O. Tyrrell,

Telephone : London Wall 4003

Cables & Telegrams Natbanger London

Head Office Representatives in London

E. Akinwunmi Doherty.

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG.

A GIFT FROM HEAVEN!



BAMWO BABY MIXTURE

OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.

PRICE: 2/6 POSTAGE 1/

THE EGBA TRADING ARADAN STORES 144 DENTON STREET, P.O. Box 2, EBUTE METTA & BRANCHES

# OLOPA KO AWON TO SUN SI BUSO OJA

EBUTE-METTA - Awon enia mewa, Emmanuel Abiodun, Karimu Adotola Karimu Akano, Yesufu Muhammedu David Johnson, Lamidi Ajadi Audu Yero, Lamidi Jimo Jimo Karimu ati Jimo Ilesha, ni awon Olopa Ebute-Metta ko wa siwaju adajo fun esun wipe awon nsun si ibuso oja Oyinbo.

Adajo bu pounu meji fun enikokan ni sisan si Kotu tabi ki awon lo se ewon osu kokan bi awon ko ba ri owo san.

# Awon Ata Tete Fara Gbegba

APAPA - Awon Omo Iurin meji, John Alabi ati Amudu Yesufu ni adajo Kotu Apapa pase ki awon fun won ni buja'a meji-meji fun tete ti awon nta ni ibudo moto Iddo.

Tete ko dara e mase tete mo.

## Eleti - Ofe D'araba


**J. A. Ajao Brothers**

Head Office :- 10, Egerton Road, P. M. Bag 2278, Lagos, Nigeria. Phone -- 21941, 21521 & 21522.

OJA ILE WA: GBOGBO OJA ILE WA.

OJA ILU OKERE : GBOGBO OJA TI O NTI ILE OKERE WA

ASOJU : FUN IYEFUN - (QUAKER) - CANADA.

(b) „ IPARA TIO NTUN IRUN SE (WELLA) AG GERMANY.

(c) „ IWOSAN ARUN ERAN ATI OHUN OGBIN OKO. (GERHARDT - PENICK) ENGLAND

(d) „ ORISIRISI ODA (CONSOLIDATED PAINTS AND FANISH CORPORATION) OHIO U. S. A.

(e) „ ITOJU GBOGBO NKAN (INSURANCE) (S. B. I.) AUSTRALIA.

Awa nse iteloruu fun awon Onibara wa nipa ki ise se kia ki o si dara, atipe kia ni a nsanwo ti o ba to fun gbogbo enia.

TI KIKO ERU : A O KO ERU YIN PELU ITOJU, AO SI FI JISE KIAKIA. OPOLOPO ERU NI A NKO PELU OWO TO ROJU, OJA TI O GA, GBOGBO OHUN TI E BA RANSE NI AO SE PELU ITOJU DARADARA.


# AWON DANRAWO DI ASIKO



Awon omo egbe bolu afese gba meta ti a nwo nibu aworan yi, lati owo osi si otun Peter Brabrook, Peter Sillett ati Johnnie Brooks ti awon fi ori gba bolu wonyi nse danrawo ti o di asiko ti bolu gbigba ylo lrie nilu Oyinbo. Awon oga nipa agbabolu ni a nwo ...

# Egbe Afenifere Wole ni Ila

Ibadan-- Nipa ibo ti awon di ni ojo Tuesday ose yi fun igbimo ibile ilu Ila ni agbegbe Ile Ife: omo egbe Afenifere ni o wole ijoko marunle-logoji ninu ijoko merundinladota ti awon dibo fun. Eyokan ti o ku, enikeni ti ko fara mo egbe kokan ni o wole

Egbe Alaiuboko tile yoju rara, depo ti awon o dipo

## Iwe Irohin wa Ladun pupo

## Olawoyin Jare Ejo Re Abuse-buse

(O bẹrẹ ti iu iwe ẹsẹ to kọju)

Nwọn fi Ọgbẹni Olawọnyin sun ẹsun pe o gun Ajiṣafẹ kẹbẹ ri u ẹsu Jure ẹdun ṣẹ tẹlẹ ẹ ffi. Ninu idajọ rẹ Ọgbẹni Whitelow sọ wipe ina awọn ọlọpa ibilẹ Ilọrin ṣi lẹ o ṣeṣi ni o, tabi nwọn ti ẹmọ-ẹmọ huwa gando-gando na ni, ko bẹsi rara. O sọ pe gbogbo awọn to wa jẹri fun ijọba ni ko ni otito lẹnu, ko si ṣe gbagbọ.

Ọgbẹni R. A. Akande akọwe ẹgbẹ Talaka parapọ dapọmọ Action Group san ẹdanran pọnun (£800) si Kotu Ilọrin nigbati ko ri awọn enia mefa ti o duro fun mu wa siwaju adajọ.

LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

E M A KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE

# JAMBA ISELE SELE NILU JAPAN

JAPAN - Irohin ti a ri gbọ lati ilu Japan ni u ọsẹ to kọja ni a gbọ wipe jamba iṣẹlẹ nla kan ṣele ni iha apa Iwọ-orun ilu Japan ni Gifu.

Iṣẹlẹ na mi ilẹ pupọ to bẹ gẹ ti o fi jẹ wipe enia mẹjọ n o ku si, ti enia merinlelogbọn farapa, enia mẹta ni nwọn fi ṣe awati, awọn enia mẹta miran ti egiri wọ bo mọlẹ bi eyiti a sin'ku wọn laaye.

## Elewon Salo Nilu Onitsha

ONITSHA-Awon ọlọpa nwa Sunday Udensi, ẹlewọn kan ti o wa ninu ọgba ẹwọn ti o salọ. Agbọ pe nwọn gba Udensi si Ile Iwosan ikọ jẹdọjẹdọ nilu Onitsha, nitẹ ni o ti raje salo.

Awon olopa nwa, ẹnikẹni ti o ba ri ki o lo so fun awon olopa.

*Iṣẹ to dara!*

Iṣẹ to dara pẹlu owo ọya ti kò tàsé lo nfun ènia ni iyi ati igbesi aiye to layọ̀.

*O lé ni ẹgbã mẹsan ara Nigeria*
to mbẹ lẹnu iṣẹ to fẹsẹmulẹ labẹ

**THE UNITED AFRICA COMPANY**

THE UNITED AFRICA COMPANY
OF NIGERIA LIMITED

# Ina Lentiriki Wolu Ogbomosho

OGBOMOSHO—Ni ojo Satide tokoja ni ilu Ogbomoso ndun yungba nigbati Alaşe obun işura ilu ile ati Ina Cnimonamọna lọ şi ina titun ti awọn sese şe si ilu Ogbomoso.



Esẹ awọn Ọba, awọn Oloye ati awọn enia pataki-pataki ni o pe lati gbogbo ilu ipinlẹ Iwọ-orun Nigeria. Olotu ijọba ipinlẹ Iwọ-orun, Oloye S. L. Akintola sọ ninu ọrọ rẹ wipe ibaję ofin ati eto ipinle Iwọ-orun ni awọn fi n jo, ti awọn nje, ti awọn si nmu pẹlu ikojọpọ idunnu fun baba ati ọmọ larin erakunrin ati arabirin. Ọta ti a ngba fi ibaję ofin ati eto han ni ipinle Iwọ-orun niyẹn.



Oloye Akintola, Aşipa ilu Ogbomoso sọ ọrọ wọnyi nigbati o nfesi si iwe ikini k'abọ ti nwọn fi fun on pelu ... ijọba Apapọ, Ọlola Maitama Sule nibi ti nwọn gbe nina Lentiriki ti ijọba Apapọ fi owo gir'mọyan şe silu Ogbomoso.

# Imoran fun Gbogbo Omo Oke-Ode.

Lati Ọwọ A. R. A. ORILONISHE
Ọmọ Oke Ọde Ibini.

Mo pe gbogbo ẹnyin ọmọ Oke-Ọdẹ to wa ni Eko ati Ifẹ ati ni gbogbo ilu yoku. Mofẹ ki ẹfi arabalẹ gbọ ọrọ mi yi lati boye dada. Nitori awọn Baba wa lo ma npa owe kan bayi wipe "Bi gbọn bi ogbon laabula - amdigbo" Ọlọbọn enia miję bi ogbon lasan - Ọnọnran enia ni mọ" Toto. O re bi owe, on tipe o yẹ ki a mo nkan to tọ siwa ni ilu wa E jọ ki a ma ke gbe ita ẹ maşe jẹki a dakẹ rara Nitori wipe itiju nla nla-nla lo jẹ fun wa, lati ri wipe a o ni "Colleges" kankan kọọ wa, wọn o si ba wa tun Titi wa se atipe a nbere fun Electric Lights" a mbere "Water Pumps" sugbọn wọn ko lan fun wa. Şugbọn o jẹ eden ekan wa. Niterina e jeki a ni ifi owo sowọ pọ ki a si ni ifi enu kenu

Wo yoku loju ewe karun.

# IJA BE SILE NINU IPADE EGBE ALAKUKO.

YOTI... YE...OY

Oşitshe— Ni ọjọ Satide nibiti awọn ẹgbẹ Alakukọ ti nşe ipade gbogbo-gbo ninu Oşitsh ni agan ija nla kan be sile, ti idarudapọ wọnu ipade na, nwọn ni lati ranşẹ pe awọn ọlọpa lati wa ba nwọn d'ọrọ si.

Ohun ti o fa rukabi iju na ni awọn ẹgbẹ kan ti nje Dynamic Party, bẹrẹ pariwo kẹ'rin abuku si ẹgbẹ N. C. N. C. nibi ipade na awọn ẹgbẹ Alakukọ si dawọn lohun pada, ibẹ ni idarudapọ ti bẹre.

A gbọ wipe nkan to han ti o jẹ ti ọmọ ẹgbẹ Dynamic Party ni nwọn baję, ọlọpa ko ma ẹ itọka ninu wọn, şugbọn nwọn pe awọn ẹgbẹ mejeji bi lere ọrọ.


# OKU'JA WOLU

NIBGATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ŞE LE RA OMIRAN EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE ŞE TI OJA RẸ YIO FI MA TA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

Polowo Oja Nyin
Sinu Iwe Irohin
ELETI-OFE

# ENITO NI MOTO W'EWON OLE AJI BASIKULU

o——oo—o——o

ADO EKITI — Onimọto ti awọn nre ni Ọgbẹni Egbue ni nwọn ju s'ẹwọn oṣu meji-din-logun ni Kotu Ado Ekiti ninu ọsẹ tokọja lori Kẹkẹ Olugere (Bicycle) Raleigh o ji pọnun meji-le-logun ati ṣile mẹwa ti o ji.

Awọn ọlọpa sọ wipe Egbue fi mọto rẹ dabu ọna fun ọmọde ti o ngun basikulu bọ' o si fi agbara gba basikulu na. Egbue ṣọ wipe on gba basikulu lọwọ ọmọ na nitoripe on fẹ gun lọ si abule ti ọna ko gba mọto ni.

Egbue si tun wipe ẹru ọja oni rinwo pọ un ni o ni ṣe awati ninu mọto on lowurọ jọ keji.

# Okunrin Kan W'ewon L'ekeji-din-logun

xox——x vox——xox

ILE IFẸ — Ọkunrin kan ti oruko rẹ njẹ Yesufu Owojuri ni ọlọpa mu wa siwaju adajọ Kotu ibilẹ ni Ile-Ifẹ lori ẹsun mẹta fun ole jija ati awọn irin iṣẹ ti nwọn fi nja ole ti o ni lọwọ.

Gẹgẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ro mọ lọrun, ni wipe o ji orisirisi ẹru ko, pẹlu agogo ọkun owọ igo Tadawa ati obẹ ninu mọto akẹru an ti o wọ jati Eko de Ile-Ifẹ ni ọjọ edogun oṣu June ọdun ni.

Ninu idajọ rẹ, adajọ Kotu Ọgbẹni S. A. Fawẹhinmi sọ wipe ẹdaran burruku, ole ni ẹ, bi o ṣe pe mo lagbara tu bẹ ni, mba jẹ ki o lo iyoku ọjọ ori rẹ ninu ọgba ẹwọn. Ki o lo s'ẹwọn fun ọgbọn oṣu tabi ki o lọ ṣe ọgbọn oṣu ninu ẹwọn.

# Imoran Fun Gbobbo Omo Oke Ode

Lati Ọwọ :- A. R. A. ORILOISHE

ỌMỌ OKE ODE IDẸRA.

vo——vov——vov——ov

Ki wọn le dawa lehun atipe gẹgẹbi imọnran ti emi fẹ fun yin nipe ẹlẹki a pa ti Mọṣalaṣi t nisisyi ki aṣẹ agbara lati le ko "Primary School" ati "Colleges" si ilu wa. Ẹ wo iru Iya ti awọn Baba wa ti jẹ siwaju ati siwaju, iru awọn ti mo fẹ daruko wọnyi won ti se op lopo wahala jinna-jinna fun ilu wa.

1. Sanni Dongo, 2. Alhaji M. A. Ọpẹloyẹru, 3. Baraiaoh Baba Aarfi 4. Alfa Salawu 5. Bello

Paranti ati iru awọn Brother wa bo bo Won nawo wọn tun nara sugbọn ko pe gbogbo Ẹnyin akẹkọ ilẹ wa, awọn Baba wa ti sin wa jinna, o yẹ ki awa na wa mura ki atiji kuro ninu okunkun. Ẹ jọwọ, ẹ maṣe sọ wipe ọrọ mi na npọju nitori awọn Baba wa lo tun pa Owe kan bayi wipe "Bi Ina ko ba tan lasọ, Ẹjẹ ko le tan ni ekanna"

Mofẹ ki ẹ mọ daju wipe ọwọ ẹnyin ẹgbọn wa ati ẹyin aburo wa l'o ku si, ẹnyin na ẹ wo ibi ti aiye lọju de nisisiyi, abuku lo jẹ fun wa lọdọ wa nitorina, A'lagẹ ọ ti bimọ rẹ, aimọjo ku si lọwọ.

Ẹ jọwọ mo bẹ yin ẹlẹki atunbọ mura e mase jẹki o rẹ wa rara adura mi si yin nipe gbogbo erongba wa lori owo ni, Oluwa Olodumare yio ro gbogbo wa lorun e, Ile ko ni lewu, Ọna ko ni nawa iṣẹ wọ ọ gbogbo lẹ lgb mina, ako ni ri aṣare pa i'e o

Ẹnyin yio tun ma gbọ ọrọ mi yoku l'ọsẹ to mbọ.

Ipade wa bi Oyin o.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"

Fun Itọju ti bi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi aton amodi wọnyi ba nyọ o lẹnu Ẹhin didun eri ile itọ itọ jijo enia, itọ riro, rukuruku Pipọn tabi riran, la uregbe, Ibaradi wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu, tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko la gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi bawọ yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kia kia ti aiafia yo si de si ọ. Meji rẹ ko si ri Ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni anfun ọ, maṣe gba rara o!



Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6
Owo okọ ṣile meji abọ (2/5d)
Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni :-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos, Phone: 22878 Nigeria.
( Ọja Ita Faji)

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN :-
158 OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA-AIYEBAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN.

## LEVENTI STORES MARINA

As from the 28th August 1961 we shall be introducing the following

NEW BUSINESS HOURS . . .

• • • • • • • • • • • •

| | | |
|---|---|---|
| -x- Mondays | 8 a.m. - 12.30 p.m. | 2-4.30 p.m. |
| -x- Tuesdays | 8 a.m. - 12.30 p.m. | 2-4.30 p.m. |
| -x- Wednesdays | 8 a.m. - 2.30 p.m. | Closed |
| -x- Thursdays | 8 a.m. - 12.30 p.m. | 2-4.30 p.m. |
| -x- Fridays | 8 a.m. - 12.30 p.m. | 2-4.30 p.m. |
| -x- Saturdays | 8 a.m. - 1 p.m. | 3-5.30 p.m. |

The above will apply to our

COLD STORE, SUPERMARKET,

ELECTRICAL — DEPARTMENT STORE

AT YOUR SERVICE

LEVENTIS STORES

MARINA & MAINLAND


# MOTO GBINA ENIA MEFA KU.

Ilesha— Ni ojo Atalat (Tuesday) ni a gbo wipe Moto ak'ero kan ti awon eniyan npe ni "Kia-kia bus" ti Nomba re je W. A. C. 117, ti o bere irin ajo lati Ilesha lo si Ile-Ife, o ri so igi Jicko nla kan l'ona ilu Ilesha si Ile-Ife, o si gbina lesekese.

Enia mefa ni ina jo pa ninu awon ero to wa ninu moto na, eni marun si farapa pupo. Nwon ko iku awon ti ina jo pa na lo si Ife. Ayewo oku ninu Oshogbo, awon ko si ti iri moto mo won. Awon marun to farapa ni nwon ko lo si Ile Iwosan awon Ijo Afi Seventh Day ti o wa ni Ile-Ife fun itoju.

Awamoto ak'ero na ni ina jo pa bimbamu, afi awon omo ikose re meji ti nwon yo lai farapa. Atile gbo wipe awon jona depo ti yio soro lati mo won.

Odomobin in kan ti nwon da ojo igbeyawo re sona ti o je okan ninu awon ti o farapa si fun Onirohin wa pe on pelu awon obi re nwo Moto na lati Ilesha nlo si Ile-Ife lati lo ra nkan iyawo ki on ni janmba yi sele.




PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of siding) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 260 and more stations.

And what's more . . . you are dealing with people you can trust.



SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL




Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P. O. Box 407 Phone No 23370